**15.** Ọ̀rọ kò ri bẹ, ti kò ba ṣiwọ, dajudaju A o fi àṣoṣo rẹ̀ wọ ọ.

كَلَّا لَئِن لَّمْ يَنتَهِ لَنَسْفَعًا بِالنَّاصِيَةِ ﴿١٥﴾

**16.** Aṣoṣo ori opurọ, ẹlẹsẹ̀.

نَاصِيَةٍ كَاذِبَةٍ خَاطِئَةٍ ﴿١٦﴾

**17.** Ẹ jẹ ki o pe awọn alabaro rẹ̀.

فَلْيَدْعُ نَادِيَهُۥ ﴿١٧﴾

**18.** Awa yio pe awọn ọmọ̀ ogun (Wa) ti nwọn le koko.

سَنَدْعُ ٱلزَّبَانِيَةَ ﴿١٨﴾

**19.** Bẽkọ, ma tẹle tirẹ̀, fi orikanlẹ̀ (fun Ọlọhun) ki o si sunmọ Ọ.

كَلَّا لَا تُطِعْهُ وَٱسْجُدْ وَٱقْتَرِب ۩ ﴿١٩﴾

## *(97) Suratul - Kọdri*

## سُورَةُ ٱلْقَدْرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Dajudaju Awa la sọ ọ (Al-Kurani) kalẹ̀ ni Oru Abiyi.

إِنَّآ أَنزَلْنَٰهُ فِى لَيْلَةِ ٱلْقَدْرِ ﴿١﴾

**2.** Kini ohun ti o le mu ọ mọ ohun ti Oru Abiyi nã jẹ?

وَمَآ أَدْرَىٰكَ مَا لَيْلَةُ ٱلْقَدْرِ ﴿٢﴾

**3.** Oru Abiyi nã, o ni õre ju ẹgbẹ̀run òṣù lọ.

لَيْلَةُ ٱلْقَدْرِ خَيْرٌ مِّنْ أَلْفِ شَهْرٍ ﴿٣﴾

**4.** Awọn Malaika ati Ẹmi nã (Jibreel tabi Malaika miran) nsọkalẹ̀ ninu rẹ̀ pẹlu iyọnda Oluwa wọn fun gbogbo ọ̀rọ̀ kọ̃kan.

تَنَزَّلُ ٱلْمَلَٰٓئِكَةُ وَٱلرُّوحُ فِيهَا بِإِذْنِ رَبِّهِم
مِّن كُلِّ أَمْرٍ ﴿٤﴾

**5.** Alãfià ni titi ilẹ̀ yio fi mọ.

سَلَٰمٌ هِىَ حَتَّىٰ مَطْلَعِ ٱلْفَجْرِ ﴿٥﴾

## *(98) Suratul - Bayyinah*

## سُورَةُ ٱلْبَيِّنَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Awọn ti kò gbagbọ ninu onitirà ati awọn ọṣẹbọ, nwọn kò yẹ

لَمْ يَكُنِ ٱلَّذِينَ كَفَرُوا۟ مِنْ أَهْلِ ٱلْكِتَٰبِ وَٱلْمُشْرِكِينَ